Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras
São Francisco do Conde (BA) | vol. 5, nº Especial I | p. 228-234 | jan./ jun.2025.

# Ètò ìṣirò aládàdé-méjì àti àmúlùmọ̀là odù ifá

# O sistema numerológico e de dois dígitos do Rio Ifa

**J. Gbenga FÁGBỌ́RUN, PhD** *

ORCID iD https://orcid.org/0009-0009-3206-6227

ÌBÀ/ÌKÍNI
Eríwoyà o.
Àbọrú, àbọyè, àbọṣíṣẹ.
Oṣó ilé, mo júbà baba mi.
Àjẹ́ ilé, mo júbà baba mi – ọmọ Anífálájé Ọ̀kẹ́ Ọ̀rúnmìlà.
Ọmọ Alákeji bàbá òjò.

**ÀṢAMỌ̀**
Ètò ìṣirò aládàdé-méjì, gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àgbékalẹ̀ Odù Ifá, ni a ó lò fi ṣàlàyé bí Odù Ifá ṣe ń hù jáde lójú ọpọ́n nígbà ti a bá dá ifá kalẹ̀. A lo ìmọ̀ ìgbàlódé bí ó ṣe wà nínú ẹ̀kọ́ tó jẹ mọ́ àdàdé-méjì, ìyẹn akọ àti abo (+ àti -) tí wọ́n lo èdè kọ̀ǹpútà kọ bá yìí: 'I' ati '0'. Ohun tó ń ṣẹlẹ̀ nínú ìmọ̀ ìgbàlódé tó jẹ mọ kọ̀ǹpútà ti ranirú àlàyé tí a lè ṣe nípa bí Odù Ifá ṣe ń hù. Àwọn baba mi ni 'agbéyìnkùlé-mọye-odù-tó-hù'. Inú kọ̀ǹpútà ló kù tí àwa yóò ti máa mọ Odù tó hù. A kò níí lo 'II' fún abo (-) nínú iṣẹ́ wa yìí ní ìbámu pẹ̀lú èdè tí kọ̀ǹpútà gbọ́. Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀, abo mẹ́jọ àti akọ mẹ́jọ ló wà nínú ọ̀pẹ̀lẹ̀ àti àwọn ohun èlò mẹ́ta yòókù tí a lò fi ṣàlàyé Ifá dídá nínú iṣẹ́ yìí. Nítorí pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni ẹ̀rù máa ń bà nígbà tí wọ́n bá rí ọ̀pẹ̀lẹ̀ ni a ṣe lo obì àbàtà, owó-ẹyọ àti owó pa-unpa-un-ṣílè fi ṣe ìwádìí nǹkan lọ́wọ́ Ifá. Àjọṣepọ̀ tó wà láàrin akọ àti abo yìí ló bí gbogbo ọ̀tà- lérúgba-ó-dín-mẹ́rin (256) Odù Ifá nígbà tí a bá ṣe àmúlùmọ̀là Odù méjì àkọ́kọ́ tí a gbà pé àwọn ló bí Odù yòókù. Ogbèyẹ̀kú ni baba àmúlù. Èyí ni wọ́n ń kọ ní ọlọ́kọ̀ gbọọrọ bá yìí ní èdè kọ̀ǹpútà: 0101010101010101. Wọ́n sì le tò wọ́n wá sílẹ̀ ní olóòró (àtòwálẹ̀) bí a ṣe rí i nínú Odù Ifá ("Permutation," 2021). Ìmọ̀ kejì tí àwọn Babaláwo/Ìyánífá ń lò fi ṣẹ̀dá Odù Ifá ni ètò àmúlùmọ̀là tó jẹ mọ́ àtúnwí àti àmúlùmọ̀là aláyọsíra bí a ṣe rí i nínú àwọn Odù Ifá tó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:

1 1 0 0 0 I I 0
1 1 0 0 0 I I 0
1 1 0 0 0 I I 0
1 1 0 0 0 I I 0

Ai (Èjì Ogbè) Aii (Òyẹ̀kú Méjì) Bi (Ogbè Òyẹ̀kú) Bii (Ọ̀yẹ̀kú Ogbè)
Nínú àpẹẹrẹ Ai àti Aii, àmì Ifá tó wà ní ọwọ́ ọ̀tún jẹ́ irúkan náà pẹ̀lú ti ọwọ́ ọ̀rọ̀ (ọwọ́ àlàáfíà, ọwọ́ òsì) láti ṣẹ̀dá Ojú Odù. Èyí ni a tún le pè ní àmúlùmọ̀là ẹlẹ́dà. Nínú àpẹẹrẹ tó wà ní Bi àti Bii apá méjì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀ láti ara Odù Ifá méjì ló para pọ̀ da Àmúlù Odù (Ọmọ Odù) kan ṣoṣo.

Ká ní a kò mọ irú Odù tó hù, a le lọ wo inú Ẹní Ifá Àtẹ Ọrúnmìlà. Iṣẹ́ ń lọ lórí eléyìí lọ́wọ́, ṣùgbọ́n ẹ le wo inú ìwé tí àwọn ènìyàn kan ti kọ bí àpẹẹrẹ *256 Odu Ifa Divination*

---

* Language and Linguistic Science, Project and Financial Executive Director, Peacemaker International, Bradford UK. Dr J. Gbenga Fagborun (popularly known as Baba Joel on social media) is a professional linguist with Doctor of Philosophy (D.Phil) in Language and Linguistic Science from the University of York, UK. He was awarded BA 1st Class Hons in Yoruba in 1982 from the University of Ife (now Obafemi Awolowo University, Ile-Ife). He was awarded the most prestigious Commonwealth Scholarship in 1987 to study in the UK. E-mail: virgocaps5257@gmail.com

*Cards Companion Book* ( 256 Cards - sixteen sets | 256oduifa.com ) (kò ní ọdún kíkọ) láti ọwọ́ Akanbi Ọmọ Amọkẹ ati Afọlabi Lipẹde) tabi ki ẹ lọ wo inú ẹ̀rọ ayélujára íntánẹ́ẹ̀tì. Ohun tí yóò kàn ni kí a wa ẹni tó le ki Odù tó hù náà. Lọ́jọ́ iwájú, gbogbo ẹsẹ Ifá ni a ó ṣe àkójọpọ̀ wọn sínú ẹ̀rọ. Èròǹgbà wa lórí iṣẹ́ yìí ni ki a fi ọ̀nà han kóówá kí wọ́n le ṣe ìwádìí nǹkan lọ́wọ́ Ifá fúnra wọn. A gbà pé ìṣíkà tàárà tí a lè fi bá àwọn ẹ̀mí àìrí sọ̀rọ̀ ni ìlò ètò ìṣirò aládàdé-méjì àti ètò àlámùúlùmọ̀là jẹ́ gẹ́gẹ́ bí a ṣe rí i nínú àgbẹ́kalẹ̀ Odù Ifá.

ÌFÁÀRÀ

Àká imọ̀ ni Odù Ifá jẹ́, èyí tó yẹ kí a máa kọ́ nípa rẹ̀ láti iléèwé alákọ̀ọ́bẹ̀rẹ. A tilẹ̀ gbọ́ wí pé àwọn ará Ṣáína kan ti bẹ̀rẹ̀ sí̩í dífá. Láìpẹ́ ni àwọn àjèjì wọ̀nyí yóò gbé Ifá wa wọnú ẹ̀rọ. Baba-baba mi ni wọn ń kì ni ‘Anífá-ọlọ́jà-níkùn’. Kò sí ohun tó mú àwa ọmọ rẹ̀ tí a kò níí fi mạa jẹ́ ‘Anífá-ọlọ́jà-nínú-ẹ̀rọ’. Ara ohun pàtàkì tí a fẹ́ fi ìmọ̀ kọ̀ǹpútà ṣe nìyí. A gbọ́dọ̀ bá a dé ibi tí a ó ti tẹ bọ́tìnnì, tí Odù Ifá kan yóò ì yọ. Dandan ni kí Odù Ifá kan hù ni gbogbo ìgbà tí a bá da Ifá nítorí pé ọ̀pẹ̀lẹ̀ kìí balẹ̀ kí ó máà gbẹbọ. Ìmọ̀ ìṣirò tí wọ́n tẹ̀le nínú Odù Ifá ló jẹ́ kí eléyìí dá wa lójú. Sáyẹ̀ǹsì ni.

Ọ̀kan lára ọgbọ́n àti ìmọ̀ tí àwọn baba wa ń lò pé kí wọ́n fi gbọ́ ohùn Ọlọ́run - ẹni tí ó mọ ìparí ohun kí a tóó bẹ̀rẹ̀ rẹ̀. Òun ló mọ iwájú ohun tó sì mọ màrín-rín ohun gbogbo. Kò sí ẹni tí kìí fẹ́ mọ ohun tí Ọlọ́run fẹ́ kí wọ́n ṣe. Àfi àwọn tí kò gba Ọlọ́run gbọ́ rárá.

**ÀṢÀ ÀTI Ẹ̀SÌN**

Ó yẹ kí a fi yé ara wa pé àṣà yàtọ̀ sí ẹ̀sìn bí ọ̀rọ̀ bá kan ọ̀rọ̀ àfọ̀ṣẹ àti ìwòye ìmọ̀ ti a tún ń pè ní yẹ̀míwò. Nínú Bíbélì Mímọ́ gan-an, wọ́n tọ́ka sí ìlò URIMU àti TUMIMU bí ohun èlò tí wọ́n fi ń ṣe ìjẹ́rìí òdodo, pé bóyá ẹni kan jàre tàbí ó jẹ̀bi (Ekisodu 28:30). Àwọn kan tilẹ̀ sọ pé ó wà lára ohun mímọ́ tí wọ́n kó sínú Àpótí Ẹ̀rí. Àwọn Olórí Àlùfáà ń lò ó ní Jerúsálẹ̀ẹ̀mù pé kí wọ́n fi gbọ́ ohùn Ọlọ́run. Níbo ni a kó tiwa sí? A kó o sínú ọ̀pẹ̀lẹ̀, owó ẹyọ, obì àbàtà àti owó pa-unpa-un-ṣílè. Ìgbénde àti àtúnbí Ifá ni a fi àkànṣe iṣẹ́ yìí ṣe. Ìlò Urimu ati Tumimu yìí kò yàtọ̀ sí ìlànà aládàdé-méjì nítorí pé wọ́n ń tọ́ka sí dúdú àti funfun bí àwa náà ṣe ni akọ àti abo, ìmọ́lẹ̀ àti òkùnkùn, orí àti ìrù bí a ṣe rí i nínú ìmọ̀ ìṣirò aládàdé.

Ọ̀kan lára ohun tó ṣe àkóbá fún ìmọ̀ wa ni pé àwọn tó ní ìmọ̀ kò fẹ́ tú u síta. A le fi nǹkan a-mọ́ púpọ̀. Kí ló dé tí a kò le wá ọ̀nà pé kí Odù Ifá da ohun tí ó rọrùn fún tawo-tọ̀gbẹ̀rì pé kí wọ́n mọ̀. Kí a máa mú ọ̀pẹ̀lẹ̀ lọ́wọ́ bí àwọn onígbàgbọ́ ẹlẹ́sìn Mùsùlùmí ṣe ń fi tẹ́súbíyù yangàn, tí àwọn Páàdì ń lo ìlẹ̀kẹ̀ àdúrà. Ọ̀pẹ̀lẹ̀ ṣá ni a mọ̀ sí agbẹnusọ fún Olódùmarè. Èyí ló jẹ́ kí ó mọ iwájú ohun ati ẹ̀yìn ohun. Òun ni òòtọ́ ayé kù sí lọ́wọ́.

Ẹ máà ṣe jẹ́ kí ó yà yín lẹ́nu pé èdè tí wọ́n fi kọ kọ̀ǹpútà lónìí ti wà nínú Odù Ifá láti ìgbà ìwáṣẹ̀. Èyí ni àwa pè ní ìlànà ALÁDÀDÉ-MÉJÌ ati ÀMÚLÙMỌ̀LÀ ODÙ. Àmúlùmọ̀là le jẹ̀ èyí tí a ṣe ẹ̀dà (àtòpadà) Odù tó wà lápá ọ̀tún ní apá òsì. Eléyìí ló ń bí OJÚ ODÙ. Ó sì le jẹ́ àmúlùmọ̀là aláyọsíra. Èyí ni ìgbà ti odù apá ọ̀rọ̀ ba yàtọ̀ si ti apá ọ̀tún. Eléyìí ló ń bí ỌMỌ ODÙ.

ÀYỌRÍSÍ ÌWÁDÌÍ WA:

A le fi Ẹní Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà ṣe:

(a) káàdì Yẹ̀míwò (spiritual consultation)

(b) káàdì Ìṣeré (playing cards) oríṣiríṣi

Ìwádìí fi hàn wa pé kò sí káàdì yẹ̀míwò kan tó kún ju èyí ti a pàtẹ rẹ̀ sí orí Ẹní Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà. Bi a ba parí iṣẹ́ yìí tán, Odù kọ̀ọ̀kan ló máa wà nínú káàdì ọ̀tọ̀ọ̀tọ̀. Tó fi jẹ pé bí a bá yọ̀rọ̀ káàdì pọ̀ tán, a le fi mọ ohun ti yóò ṣẹlẹ̀ lọ́jọ́ iwájú láti ipasẹ̀ Odù tó wà nínú káàdì.

Àwọn Àkànbí Ọmọ Àmọ̀kẹ́ ati Afọlábí Lípẹ̀dé ( 256 Odu Ifa Divination: Amazon.co.uk: Omo Amoke, Akanbi, Lipede, Afolabi: 9798327930551: Books ) ti bẹ̀rẹ̀ irú iṣẹ́ yìí ní èdè Gẹ̀ẹ́sì.

## ÀKỌ́SÓRÍ ODÙ IFÁ

Nígbà ti a ba fẹ́ dẹ́rù ba àwọn ènìyàn, a le sọ pe gbogbo Odù Ifa 256 ni a gbọ́dọ̀ kọ́ sórí. Bẹ́ẹ̀ kọ́! Ohun ti a nílò gan-an ni àkọ́sórí Ojú Odù 16 bí a bá fẹ́ kọ́ nǹkan sórí rárá. Eléyìí kò ṣòro nitori pe gbogbo rẹ̀ ni àwa wa ọ̀nà tó rọrùn kọ́ sórí ní ṣíṣẹ̀ntẹ̀lé nígbà ti a ń kẹ́kọ̀ọ́ lọ́jọ́ un. Bí a bá ti mọ Ojú Odù 16, àmúlùmọ́là wọ́n ni yóò fún wa ni Ọmọ Odù 240. Bí àpẹẹrẹ, ẹni bá ti mọ àmì Ọ̀bàrà Méjì to si mọ ti Ọ̀kànràn Méjì ko le ni ìṣòro pe kí òun ṣẹ̀dá Ọ̀bàrà Ọ̀kànràn tàbí Ọ̀kànràn Ọ̀bàrà. Ìyẹn ni pé a kò nílò pé kí a kọ Ọ̀bàrà Ọ̀kànràn sori lọ́tọ̀. Kò nira àtilò fún àwọn tí a ti fi ìlànà yìí hàn.

## ẸLẸ́RÌÍ MÉJÌ

Ẹni kan béèrè pé kí ló dé tí Odù Ifá máa ń jẹ́ méjì-méjì. Ìlànà ìmọ̀ ìṣirò aládàdé méjì – (akọ ati abo) ni àwọn Awo/Ìyánífá máa ń tẹ̀lé dífá. Ẹyọ mẹrin yoo wa ni apátùún-apásì ọpọ́n Ifá.Ìdí mìíràn ni wí pé ẹnu ẹlẹ́rìí méjì tabi mẹ́ta ni a ó ti fi ìdí òdodo múlẹ̀ (Deutaronomi 19:15, Kọrinti 13:1).

Bí a ṣe sọ tẹ́lẹ̀, akọ mẹ́jọ ati abo mẹ́jọ ni ọ̀pẹ̀lẹ̀ ní. Ọ̀kan kò ju èkejì lọ. Wọ́n gbọ́dọ̀ jọ jẹ́rìí sí ohun ti a ń wádìí rẹ̀ ni. Bí kìí bá ṣe ẹni bá wẹjú, tó sì ní ìmọ̀ mìíràn ti a kò le sọ̀rọ̀ púpọ̀ nípa rẹ̀ ninu iṣẹ́ kékeré yii, kò si ẹni to le mọ Odù Ifá tí yoo hù kí ó tóó dá Ifá. Akọ mẹ́jẹ̀ẹ̀jọ le hù pa-pọ; bẹ́ẹ̀ ni abo náà le hù pa-pọ̀. Ó sì le jẹ àmúlùmọ́là akọ ati abo. Ṣùgbọ́n àwọn baba tiwa ni AGBẸ́YÌNKÙLÉ-MỌ-IYE-ODÙ-TÓ-HÙ. Iyẹ́n ni pé àwọn tó wà ninu ilé ti gbọ́dọ̀ máa dáfá lọ́wọ́ kìí ṣe kí wọn tóó dáfá.

## ÈDÈ KỌ̀ǸPÚTÀ

Ọ̀kan ninu ohun ti a ní tí a kò nàání ni ìlànà ìṣirò aládàdé-méjì ati àmúlùmọ́là Odù Ifá jẹ́. Èyí ni àwọn kan ji wò tí wọ́n sọ da èdè kọ̀ǹpútà fún gbogbo ayé lónìí. Òun ni wọn fi kọ ohun tó wà ninu kọ̀ǹpútà àgbéléṣẹ̀, síkéèlì onídígítà ati fóònù ti a ń lò gbogbo ati àwọn ẹ̀rọ ti a ti ń tẹ bọ́tìnnì tó fi kan ATM ti ń gbé owó jáde.

'I' (akọ) àti 'O' (abo) ni a lò ninu isẹ́ yii ni ìbámu pẹ̀lú àmì èdè kọ̀ǹpútà. Èyí ni àwọn Awo ilẹ̀ Bíràsíì ń lò dípò 'II' ti àwọn Awo kò dẹ́kun-ún lò nílẹ̀ Yorùbá Nàìjíríà (Lọ wo TODO SOBRE LA RELIGION YORUBA OSHA E IFA - OSHAEIFA.COM ).

## ÌTÀN ÌṢẸ̀DÁ ÌṢIRÒ ALÁDÀDÉ-MÉJÌ

Ìlò ìlànà ìṣirò aládàdé-méjì àti àmúlùmọ́là kìí ṣe ohun tuntun. Láti ìgbà ìwáṣẹ̀ ni àwọn baba wa ti mọ̀ nípa rẹ̀. Èyí wà lára ohun tó tọ́ tó sì yẹ kí a fi yé àwọn èwe wa. Ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn ni kò le mọ èyí nítorí pé ṣe ni a ń gbé Ifá pa-mọ fún aráyé. Awo ni wọ́n fi i ṣe. Yorùbá ti ń lo ìlànà yìí kí àwọn Gẹ̀ẹ́sì ati àwọn òyìnbó yòókù tó gbọ́ nípa rẹ̀ ní sẹ́ńtíúrì kẹtàdínlógún nígbà tí arákùnrin kan - Gottfried Wilhelm Leibniz ará ilẹ̀ Jámánì ní ọdún 1689 ( History of the Binary Number System - Convert Binary ) ṣiṣẹ́ lórí rẹ̀. Ohun tí a ń gbé pa-mọ ti wọnú kọ̀ǹpútà. Kìí ṣe ohun bònkẹ́lẹ̀ ti a le fi máa ṣe 'awo' mọ́, bí a kò bá fẹ́ kí wọ́n já a gbà tán lọ́wọ́ wa.

Bí wọ́n bá sọ pe àwọn kò jí wa wò, a jẹ pe a ti ní tiwa ṣaájú tiwọn. Ṣùgbọ́n àwa kò ká a sí. Àmọ́ sá, o bà ni kò ì bà jẹ́. A sì le lò ó fi kọ́ àwọn èwe wa ni ìlànà òde-òní bí ẹni pé a ń ṣeré. Ara ohun tó yẹ kí a mọ̀ ni pé àmúlùmọ́là Èjì Ogbè ati Ọ̀yẹ̀kú Méjì ló fún wa ni Ojú Odù mẹ́rìnlá yòókù. Ohun ti o mu wa sọ bẹ́ẹ̀ ni pe kò sí inú Odù ti ẹ kò ti níí rí akọ (I) tíí ṣe àmì Ogbè ati abo (O) kan tíí ṣe àmì Ọ̀yẹ̀kú. Àmúlùmọ́là Ojú Odù 16 lo fun wa ni Ọmọ Odù 240 (òjì-lé-rúgba). Àpapọ̀ Ojú Odù ati àmúlù Odù jẹ́ 256 (ọ̀tà-lé-rúgba-ó-dín-mẹ́rin), èyí tó jẹ nańbà pàtàkì ninu ìmọ̀ ìṣirò aládàdé-méjì bí ó ṣe wà ninu èdè kọ̀ǹpútà. Fọ́múlà wà fún èyí tí a ó máa fi-hàn lọ́jọ́ iwájú ( https://www.geeksforgeeks.org › binary-formula). Àmúlùmọ́là Odù Ifá ati Àdàdé-méjì tí a ń wí yìí bẹ̀rẹ̀ lórí OGBÈ:

1

4
1
1
1
ati Ọ̀YẸ̀KÚ
0
0
0
0

Àmúlùmọ̀là OGBÈ ló fun wa ni ÈJÌ OGBÈ:
1 1
1 1
1 1
1 1

Àmúlùmọ̀là Ọ̀YẸ̀KÚ ló fún wa ní Ọ̀yẹ̀kú Méjì:
0 0
0 0
0 0
0 0

Bí a ṣe tò ó pọ̀ nínú Ẹní Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà, àmúlùmọ̀là Ogbè ati Ọ̀yẹ̀kú ló bẹ̀rẹ̀ híhù Odù Ifá yòókù. Ogbèyẹ̀kú ni baba Àmúlù. ìyẹn ni apá kan Ogbè apá kan Ọ̀yẹ̀kú tó wà ní ìsàlẹ̀ yìí:
0 1
0 1
0 1
0 1

Bí ó bá ṣe Ọ̀yẹ̀kú ló kọ́kọ́ hù lójú ọpọ́n Ifá, a ó rí Ọ̀yẹ̀kú Ogbè:
1 0
1 0
1 0
1 0

ÌLÀNÀ IFÁ DÍDÁ
Bí a bá ti dá Ifá kalẹ̀ pé kí a mọ Odù tó hù, a le lọ wo inú Ẹní Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà tí ó ní àkójọpọ̀ gbogbo Odù 256. Àwa ní eléyìí ní ìkáwọ́ ṣùgbọ́n kò sí àyè fún àfihàn rẹ̀ nínú àpilẹ̀kọ yìí. Ìtọ́wò lásán ni ohun ti a kọ sílẹ̀ níbí. A sì ń méyẹ bọ̀ lápò ni, pé bóyá a le ri àwọn onímọ̀ ti yóò fẹ́ dá sí i.
Bí a bá ti fẹ́ ṣe àyẹ̀wò fúnra wa bá yìí, a gbọ̀dọ̀ tẹ́ Ẹní Ifá kí a sì pa Àtẹ Ọ̀rúnmìlà. A kò nílò kí a máa kọ́ ọ̀pọ̀lọpọ̀ Odù Ifá ati àmì wọn sórí. Bí Odù kan bá hù jáde, ẹ wo orúkọ rẹ̀ ninu Ẹní Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà. Ẹ lọ wo bí wọ́n ṣe kì í nínú ìwé ìmọ̀ Ifá. Ó yẹ kí a ti ní ìwé tó máa dúró
bí bíbélì fún àwọn adífa. Àwa náà ní èyí tí a ń tò pọ̀ lọ́wọ́. Bí kò bá sí ìwé Odù Ifá ní àrọ́wọ́tó, ẹ le bi àwọn Awo tó bá wà ní itòsi. Àwa ṣe irúfẹ́ iṣẹ ìwádìí yìí lórí Ọ̀bàrà Ọ̀kànran. A ó sọ̀rọ̀ ráńpẹ́ lóri eléyìí níwájú.

OHUN ÈLÒ ÌDÍFÁ
Àwọn kan béèrè pé kí ló dé tí a kò lo ọ̀pẹ̀lẹ̀ ninu iṣẹ́ yìí. Ohun ti a wí fún wọn ni pe a kò fẹ́ fi

ohun ìṣẹ̀ǹbáyé ṣerémọdé. Àwọn èwe wa ni a fẹ́ kọ́ ní ìlànà Ifá kìí ṣe ẹ̀yin àgbà Awo nitori pé a kò tó yín kọ ní Ifá. A fẹ kí Ifá da ohun àtẹ́wọ́gbà ni a ṣe fọ́ ọ sí wẹ́wẹ́. Ẹni bá fẹ́ kọ́ ìjìnlẹ̀ Ifá gbọ́dọ̀ tọ àwọn Awo ati Ìyánífá lọ nítorí pé ohun ti àwọn onímọ̀ kọ sínú ìwé kò tíì tó nǹkan. 'O-kù' ni ìbọn-ọ́n dún.
Àwọn mìíràn ń lo egungun ẹran, èso igi (bí obì àbàtà), ewé tii, ìkarahun (bí owó ẹyọ) ati owó onírin tí àwa pè ni owó pa-unpa-un-ṣílè.ninu Fágbọrún (2023).

5

ÀWÒRÁN OHUN ÌDÁFÁ TÍ A LÒ
© Fágbọrún (2023)

ÒFIN TÓ DE IFÁ DÍDÁ:
Ẹ̀ẹmejì ni a gbọ́dọ̀ da Ifá bí a kò bá lo ọ̀pẹ̀lẹ̀. Mẹ́rin gbọ́dọ̀ wà lọ́wọ́ ọ̀tún ati mẹ́rin ní ọwọ́ òsì. Bí ó bá jẹ́ ọ̀pẹ̀lẹ̀, ẹ̀ẹkan tí onífá bá da Ifá ni Odù méjì máa hù – ọ̀kan lọ́wọ́ ọ̀tún ọ̀kan lọ́wọ́ òsì. Nínú ìlànà tí àwa gbé kalẹ̀ níbí, ìgbà méjì ni a ó dafá. Bí a bá fẹ́, a le pín ohun èlò tí a fẹ́ fi dafa sí ọwọ́ méjèèjì ní mẹ́rin-mẹ́rin. A sì le fi ọwọ́ ọ̀tún nìkan dà á nị ẹ̀ẹmejì. Ohun àkọ́kọ́ tí a gbọ́dọ̀ ṣe ni kí a kó ohun ti a fẹ́ fi dáfá pa-pọ̀ kí a sì ṣàṣàrò. Ìyẹn ní pé ká dánìíyàn nípa ohun tí a ń fẹ́ kí ó ṣẹlẹ̀. Bí a bá fẹ́, a le kọ́ Odù tó yọ sórí síléètì tàbí tákáàdá.

ÈRÒǸGBÀ WA
Ohun ti a fẹ́ kí ó ṣẹlẹ̀ láyé díjítà (ìmọ̀ ẹ̀rọ kọ̀ǹpútà àti àgbélẹ̀rọ-ọpọlọ) ni kí a máa lo Odù Ifá bí ohun ìṣeré kí ìmọ̀ Ifá dídá máà ba pa-run. Bí àwa bá ní àǹfàní rẹ̀, a ó jẹ kí àwọn ọmọ iléèwé aláàbídí mọ̀ nípa ìmọ̀ tó wà nínú Ifá. Ó dájú pé eléyìí yóò tún ìwà ọmọlúàbí wọn ṣe. Ó yẹ kí a le fi han àwọn èwe pé ọ̀kan lára ọ̀nà tí a le gbà bá ẹ̀mí àìrí tí a mọ̀ sí Ọlọ́run sọ̀rọ̀ ni ìlànà Ifá dídá. Eléyìí kò sọni da adẹ́bọ bí a kò bá fẹ́ dẹ́bọ tàbi pé kí a bọ òrìṣà. Bí ó tilẹ̀ jẹ́ pé àwọn Awo kan sọ fún wa pé ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn onígbàgbọ́ ẹlẹ́sìn òkèèrè (kìrìtẹ́nì àti Mùsùlùmí) ni wọ́n máa ń yọ kẹ́lẹ́kẹ́lẹ́ wá bá àwọn fún àyẹ̀wò ati ìróni-lágbára! Kí ló burú níbi kí kóówá mọ bí a ṣe le béèrè pe 'mo ń jáde lọ lónìí rèé o, bá wo ni òde yóò ṣe ri? Ǹjẹ́ kò tilẹ̀ yẹ kí a ṣe àyẹ̀wò ibi tí àgbàwọ̀ ẹ̀wù ẹ̀sìn òkèèrè bá wa dé lónìí ní ilẹ̀ Afíríkà.

ÌDÍ DA MÉJÌ LÁÀRIN OGBÈ ÀTI Ọ̀YẸ̀KÚ
Gẹ́gẹ́ bí a ṣe mọ̀, akọ tó kójú òsùnwọ̀n ni Ogbè, bẹ́ẹ̀ ni Ọ̀yẹ̀kú náà jẹ́ abo tó péye. Nígbà tí akọ tó pé ati abo tó pé bá bá ara wọn sùn, ọmọ ló kù tí a ó máa retí. 'Nígbà tí ìdí da méjì la dọlọ́mọ'. Odù Ifá ÒdíMéjì ló sọ bẹ́ẹ̀. Bẹ́ẹ̀ ló rí nípa àdàdé Ogbè ati Ọ̀yẹ̀kú tí a máa ń rí àfijọ (DNA) wọn nínú Odù kọ̀ọ̀kan, yálà Ojú Odù tabi Ọmọ Odù. Ẹ jẹ́ kí a wo àpẹẹrẹ Òfún Ọ̀bàrà (Òfún lọ́wọ́ ọ̀tún Ọ̀bàrà lọ́wọ́ òsì) yìí:
1 ----- Akọ 0 …………Abo 1 0
0 -----Abo 1 ………….Akọ 0 1
0 -----Abo 0 ………… Abo 0 0
0 -----Abo 1 ------------- Akọ 0 1
Ọ̀BÀRÀ ÒFÚN Ọ̀BÀRÀ ÒFÚN

ÌMÚLÒ OHUN TÍ A GBÉ KALẸ̀:
Lọ́jọ́ kan tí Ọ̀bàrà Ọ̀kànran jáde nígbà tí a lo obì/owó ẹyọ/pa-unpa-unṣílè, a bi àwọn Awo

léèrè ohun ti Odù yìí ń wí. Ìyẹn kókó ohun ti Ọ̀bàrà Ọ̀kànràn wí. Àwọn Awo mẹ́ta lo ki Odù Ifá yìí. Àwọn Awo tó ki Ifá lọ́jọ́ náà kò fi ojú kan ẹni ti Ifá jẹ mọ́ ṣùgbọ́n wọ́n mọ orúkọ rẹ̀ ati ti ìyá rẹ̀.
Àmì Ọ̀bàrà Ọ̀kànràn (tíí ṣe yèyé Ifá ni Odù Ifá 113 nínú Ọpọ́n Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà) nìyí:

0 1
0 0

6
0
1 0

Díẹ̀ lára àkójọpọ̀ ohun ti wọ́n wí nìyí:
1. Kí ẹni tí a dáfá yìí fún fi àsìkò rẹ̀ wá ìmọ̀, bí ó bá jẹ́ ọmọ-ìkọ́ṣẹ́. Kí ó máà máa wá owó kiri. Ìmọ̀ ni kí ó kọ́kọ́ wá.
Bí n kò bá kú, màá lówó lọ́wọ́
Ifá ni ẹ kọ́ mi
Èmi ò wówó ká
Bí n ò bá kú ma là, ma lówó lọ́wọ́
Ifá ni ẹ kọ́ mi

2. Kí ẹni náà rúbọ. Bóyá àjò ló wà; kí ó le kérè délé. Kí ó máà ba gbé sájò.
3. Ifá ní kí ẹni náà rúbọ àṣegbé. Nǹkan kan wà tó ti ṣe tó le dáràn bọni lọ́run. Kí ó rúbọ àṣegbé. ‘Àṣegbé ọmọ Èdùmàrè, ohun tí mo bá ṣe, ó ti dàṣegbé. (Wọ́n fi èyí sun ìyẹ̀rẹ̀.)
4. Wọ́n ní kí eléyìí fi ajá rúbọ. Kí ó máa sin ajá tàbí kí wọn máa bá a sìn ín. Kí ó le lé ajogun gbogbo lọ nílé rẹ̀. Ọmọ ayé kò níí kú fún un; tọ̀run yóò wa bá a níbẹ̀. Àwọn Awo sọ pé ‘bí eré, bí eré, a ti lé ikú lọ lónìí.’ (Wọ́n ń sun ìyẹ̀rẹ̀.
5. Àrùn kan tí a máa ń náwó sí ń ṣe ẹni yìí. Kí ó rúbọ. Ẹ̀kọ, àkàrà ati ọ̀lẹ̀lẹ̀ ni yóò fi kún ẹbọ rú. Kí wọ́n bá a bọ ará ọ̀run. ‘Ọ̀lẹ̀lẹ̀ mẹ́fà la fi lékú lọ lọ́jẹ̀ẹ́ o’. (Wọ́n ń sun ìyẹ̀rẹ̀.)
6. Kí eléyìí rúbọ kí ó le ba ní ẹni lẹ́yìn. Kí ó máa kó èniyàn mọ́ra nítorí pé ibẹ̀ ni oore rẹ̀ wà.
7. Ipò kan wà tí wọ́n yóò fẹ́ to ẹni náà sí; ṣùgbọ́n kí ó rúbọ kí ire tí ń wá le tẹ̀ ẹ́ lọ́wọ́.
8. Bí ẹni kan bá wà légbẹ̀ẹ́ ẹni náà tí ń ràgàn, wọ́n ní kí ó rúbọ. Ẹni náà yóò dọlọ́mọ.
9. Wọ́n ní ẹni tí Ifá yìí bá yọ sí kí ó máà máa sùn nínú òkùkùn. Kí àṣírí ọ̀tá rẹ̀ le tú lé e lọ́wọ́. Àwọn ọ̀tá bí ọ̀rẹ́. Ifá ní òun yóò gbógun ti ẹni tí ń bá iṣẹ́ rẹ̀ jẹ́.
10. Wọ́n ní kí ẹni a dífá yìí fún máà máa tijú iṣẹ́ rẹ̀. Láti ara iṣẹ́ yìí ni yóò ti là. Kí ó máà fi iṣẹ́ rẹ̀ pa-mọ́. A kìí ṣọ́jẹ̀ kí a ṣe ojú ń tì mí.
11. Bí ó bá jẹ́ ọkùnrin, ìyàwó rẹ̀ ní ipa tí yóò kó kí ó tóó le ṣẹ́gún. Kí ẹni náà sún mọ́ aya rẹ̀ pẹ́kípẹ́kí.
12. Kí ẹni náà rúbọ kí aráyé máà ba gba okó nídìí rẹ̀. Kí ó máà ba rí àìsàn abẹ́.
13. Bí ó bá jẹ́ obìnrin tí ń wá ọmọ, kí ó máà ṣe lo ìlẹ̀kẹ̀ ìdí mọ́.
14. Wọ́n ní kí eléyìí máa ṣàánú fún àwọn tó wà ní àyíká rẹ̀. ‘Òdú bí o bá jánà, kí o ran ògùnmọ̀ lọ́wọ́.’ (Wọ́n fi èyí sun ìyẹ̀rẹ̀).
15. Kí eléyìí ṣọ́ra àlè yíyàn; kí ó máà ba kọ iná sílẹ̀; kí ó lọ gbé oòrùn, tí yóò máa fi ebi pa á, níyàwó. Ifá ní:

Ẹ jẹ́ kí a ṣe igbá ilé jẹ́ẹ́jẹ́
Bí toko yóò gbó
Bí kò níí gbó, ẹnì kan kò mọ̀
A dífá fún Ọ̀rúnmìlà tí yóò ṣọkọ iná

Tí yóò máa lọ yan oòrùn lálè. (Wọ́n fi èyí sun ìyẹ̀rẹ̀).

16. Ifá ní bóyá àwọn kan ti ń robi sí eléyìí, kí ó rúbọ kí ìmọ̀ ọ̀tá máà ba ṣẹ lé e lórí.
Ara ibi tí iṣẹ́ kù sí ni bí a ó ṣe rí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn Awo tó le sọ kókó inú Odù Ifá kọ̀ọ̀kan bí a ṣe ṣe lórí Ọ̀bàrà Ọ̀kànràn yẹn. A ń wá wọn; a sì ti bẹ̀rẹ̀ síí kó wọn jọ. Gbogbo ohun tí a bá rí ni a ó kó sínú ẹ̀rọ dígítà fáráyé rí kí àwọn aláṣekù le kí wa káààbọ̀ lọ́jọ́ tí a bá fojú kanra ní ìwàlẹ̀-àṣà!.

IPARÍ

Ohun tí a fẹ́ mú jáde nínú iṣẹ́ yìí tó jẹ́ èrèdí rẹ̀ ni pé a kò fẹ́ kí ìmọ̀ Ifá da ohun ìgbàgbé. Bí a kò bá fẹ́ kí eléyìí ṣẹlẹ̀, a kò gbọdọ̀ ju ìmọ̀ Ifá sílẹ̀ fún àwọn Awo nìkan. Ó yẹ kí a ràn wọ́n lọ́wọ́ pé kí a kó ohùn ẹnu wọn jọ, kí àwọn ojúlówó àgbà Awo/Ìyánífá tí a mọ̀ tóó ṣẹ́sùn tán.
7
Ìmọ̀ kọ̀ǹpútà ni yóò ràn wá lọ́wọ́ tí ohun tí àwọn baba wa kọ́ sórí yóò fi wọnú ẹ̀rọ, ni Ifá yóò bá da ohun tó ṣeé fi yangàn láwùjọ ìmọ̀ àgbáyé.
Bí a bá ṣe àtúnṣe tó yẹ lórí ìmọ̀ Ifá, kò níí pẹ́ tí a ó fi já ara wa gbà lọ́wọ́ àwọn olórí ẹ̀sìn òkèèrè tí ń tan ayé jẹ. A ó yéé gun orí-òkè kiri. Kóówa wa ni yóò mọ bí a ṣe ń ba adániwáyé sọ̀rọ̀, tí yóò sì gbọ́.
ÌKÍNI AWO:
Àbọrú, àbọyè, àbọṣíṣẹ.
ÌDÁHÙN: Ogbó, atọ́, Ìwòrì-wòfún.

ÀKÓJỌPỌ̀ ÌWÉ ̣TI A TỌKA SÍ


Akanbi Ọmọ Amọkẹ ati Afọlabi Lipẹde (Kò lọ́dún kíkọ): 256 Odu Ifa Divination Cards Companion Book. www.Amazon.co.uk . 256 Odu Ifa Divination: Amazon.co.uk: Omo Amoke, Akanbi, Lipede, Afolabi: 9798327930551: Books
Bibélì Mímọ́ (2009): Beulah’s Bilingual & Parallel Bible (Yoruba/English). Beulah and Bible
Publishers, Ibadan, Nigeria.
Bibélì Mímọ́ (2009): Deutaronomi 19:15, 2 Kọrinti 13:1.
Binary Fomula: https://www.geeksforgeeks.org › binary-formula.
Fágbọrún, J. Gbenga (2023): Ọpọ́n Ifá Àtẹ Ọ̀rúnmìlà. Kò tíì dé orí àtẹ́.
Gottfried Wilhelm Leibniz (1689): ( History of the Binary Number System - Convert Binary )
Permutation: https://en.wikipedia.org/wiki/permutation
TODO SOBRE LA RELIGION YORUBA OSHA E IFA - OSHAEIFA.COM ).



Recebido em: 23/02/2025
Aceito em: 24/06/2025



**Para citar este texto (ABNT):** FÁGBỌ́RUN, J. Gbenga. Ètò ìṣirò aládàdé-méjì àti àmúlùmọ̀là odù ifá. *Njinga & Sepé:* Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras. São Francisco do Conde (BA), vol.5, nº Especial I, p. 228-234, jan./jun.2025.

**Para citar este texto (APA):** Fágbọ́run, J. Gbenga. (jan./jun.2025). Ètò ìṣirò aládàdé-méjì àti àmúlùmọ̀là odù ifá. *Njinga & Sepé: Revista Internacional de Culturas, Línguas Africanas e Brasileiras.* São Francisco do Conde (BA), 5 (Especial I): 228-234.